# IROHIN IMOLE

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 751. THURSDAY, JULY 23, 1964 (2D)


## Apẹja Kan Ku Sinu Omi

WARRI:— Ni Ọjọ'ru ti iṣe ọjọ kejilelogun Oṣu yi ni awọn enia to wa lẹba odo Warri si fa igbe ta nigbati awọn ri oku Ọdọ mọ'kunrin apẹja kan ti oku rẹ fo lori omi ni deede agogo mẹsan Owurọ ana, lẹhin ti gbogbo awọn enia na bẹrẹ si wọ ọdọ mọkunrin na ni nwọn ti mọ pe Brahim Akiyeni Ọmọ kunrin na njẹ.

Ninu irohin ti a tun ri gbọ lati ẹnu awọn apẹja ẹlẹgbẹ Brahim ti ye wa pe agbara awọn ti B r a h i n npa ẹja lo ti wuwo pupọ ju lati fa sinu ọkọ to fi npa ẹja na lo fa ti ko lagbara lati fa lo ba ja bọ sinu omi lojiji eyi to fi jẹ pe apẹja na lo fagba mu la le wẹ jade ninu omi na.

Lẹhin ti awọn apẹja ẹlẹgbẹ Ọdụmọkunrin na ti nṣe agbara lati ri oku rẹ gbe jade yi to jẹ pe ọwọ ati ẹsẹ Brahim ti ya kuro lara rẹ lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa ti gbe oku apẹja na lọ si ile iwosan jakulaku.

### Ọba Ọlọwọ Sọ Pe :

# MO FARAMỌ IJỌBA NITORI ONJẸ O JỌ MI

ỌWỌ:— ỌBA Ọlateru Ọlagbegi keji ọlọwọ ilu Ọwọ sọ ninu ipade ti awọn igbimọ to pari ija fun Ọba na pẹlu Ọgbẹni M A Ajasin Baba isalẹ ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ni ilu Ọwọ pe on faramọ Ijọba eyiti ẹgbẹ Dẹmọ N. N. D. P. nṣe akoso rẹ ni ipin'ẹ Iwọ Orun Najiiria nitori pe on ko fẹ ki nwọn ge owo-Oṣu on di kọbọ kan ṣoṣo l'ọdun.



OLOYE SAMUEL LADOKE AKINTỌLA
Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ—Orun ati Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

Ọba Olateru Olagbegi jẹ Ọlọwọ ilu Ọwọ jẹ Alakoso Ijọba ti ko faramọ iṣẹ kankan ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tun sọ pẹlu ohun irẹlẹ fun awọn enia rẹ pe on faramọ Ijọba t'ode oni nitoripe on ko fẹ ki onjẹ o jọ on bọ silẹ rara.

Ọba Ọlọwọ si nfun Ọgbẹni M. A. Ajasin baba isalẹ ẹgbẹ ọmọ Odudu... ti Asoju ẹgbẹ A... ni ile igbimọ aṣofin fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ni esi ẹnu ẹtẹ ti o ba lu Ọba Ọlateru Ọlagbegi keji nigbati awọn igbimọ ti yio pari ede aiyede tio wa larin Ọba Ọlọwọ ati Ọgbẹni M. A. Ajasin ati pe ki awọn mejeji le wa ninu irẹpọ eyi to jẹ pe awọn ọmọ ibilẹ ilu ọwọ lo jẹ eto ipade lati le pari ija awọn mejeji.

Ija Ọba Ọlateru Ọlagbegi keji ati Ọgbẹni M. A. Ajasin bẹrẹ lori ọrọ ilẹ kan ti awọn mejeji nijiadu eyiti nwọn si ti ko ọrọ ilẹ na de ile ejọ ti nwọn si nreti idajọ lori ọrọ ilẹ na bayi.

### ETO ALAFIA FUN AWỌN ENIA ILU



Ọba Ọlagbegi Keji Ọlọwọ Ilu Ọwọ

Ọgbẹni M. A. Ajasin ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria tun bu ẹnu ẹtẹ lu Ọba Ọlọwọ ilu ọwọ pe o nṣe ẹgbẹ oṣelu ati pe Ọba Ọlọwọ si kọ gbogbo awọn Oloye ilu ọwọ, awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre a t i ọmọ ẹgbẹ Alakukọ to wa ni ilu na lo ti ko gbogbo wọn kuro ti o si ti ko wọn lọ sẹ ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP)

Ọba Ọlọwọ ti ilu ọwọ sọ ninu ọ r ọ r ẹ p e g b o g b o ọrọ ti Ọgbẹni Ajasin sọ mọ on pe irọ ni ati pe nkan to jẹki gbogbo awọn Ọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni lati sọ ni ati pe ko si ẹgbẹ kẹgbẹ to ba le fi wa gẹgẹbi Alakoso Ijọba pe awọn ni lati faramọ Ijọba na lati le mu eto alafia wa fun awọn enia ilu na

Ninu Ọrọ Ọba Ọlọwọ si awọn Ọmọ ibilẹ ilu Ọwọ to wa sibi ipari ija na Ọba Olateru fi ye wọn pe gẹgẹbi baba gbogbo ilu p... on sẹ ileri pe on yio si ri mọ pe eto alafia ati ifokanbale rere wa ni ilu Ọwọ.

Ki ipade awọn ọmọ Ibilẹ ilu Ọwọ ti yio pari ija na to be re, edeaiyede kan be silẹ nigba ti Ọba Ọlagbegi sọ pe ki nwọn ni ki akọwe eto irohin fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilu Ọwọ Ọgbẹni Edward Gbolejoko Jackal Ogun jade kuro ninu ipade na ṣugbọn Ọba Ọlọwọ ko sọ idi rẹ ti o fi ni ki Ọgbẹni Gbolejoko jade. Sugbọn lẹsẹkẹsẹ ni Ọgbẹni Edward Gbolejoko si jade kuro ninu ipade na ti ko si sọ ọrọ kankan.

Ki awọn ọmọ Ibilẹ ilu Ọwọ to ṣe ipade lati pari ọrọ ija Ọlọwọ ati Ọgbẹni M. A. Ajasin to pari ipade ipari ija na, awọn Igbimọ ọmọ Ibilẹ ilu Ọwọ si rọ Ọba Olateru Ọ l a g b ẹ g i k e j i Ọ l ọ w ọ ti ilu Ọwọ pe ki o gbinyanju lati le tete pari ọrọ ile to daja silẹ larin awọn meji eyiti o di ọrọ ile ẹjọ pe ki o sọ fun ile ẹjọ ti nwọn pe ẹjọ na si pe nwọn yio la pari ọrọ na ni ile wọn.

Awọn Ọmọ ibilẹ ilu Ọwọ to yan igbimọ lati lọ ṣe gẹgẹbi ọrọ na yio ṣe pari larin Ọlọwọ ati Ọgbẹni Ajasin sọ pe ti Ọba Ọlọwọ ko ba gbe ọrọ na kuro ni ile ẹjọ ki o si sọ fun ile ẹjọ na pe nwọn yio pari ọrọ na awọn igbimọ na sọ pe irẹpọ ati ẹmi iṣọkan ko le wa larin Ọ b a Ọlateru a t i Ọgbẹni M A. Ajasin rara aya fi ti awọn ba pari ti ile ẹjọ na.

# Ekun Rere Idajo Oloye Awolowo ( Apa 9 )

OLOYE Awolọwọ si fi iwe ti Alakoso apapọ Ijọba Ọlọla Abubakar ti fesi iwe ti Oloye Awolọwọ kọ si i, ọrọ inu iwe na lọ bayi Oloye Awolọwọ, o ṣe ni lanu pe lemi ko tete ti da esi iwe ti o kọ si mi n i ọjọ kẹrinlelọgun oṣu kesan ọdun 1962 Nigbati ajijọ pade ni oṣu kẹjọ ọdun 1962 mo ro p e a jijọ ngbero lati fi opin s i rogbodiyan to bẹ silẹ ni ilẹ yi ṣugbọn emi ko si ma pe nṣe n i awọn kan ngbero lati da ija gbọn eyi i nwọn yio fi dite si orilẹ ede ilẹ Najiria nitori eyi e m i ko le gba e laye lati jijọ fi ọrọ jomitoro ọrọ rara Pẹlu ẹdun ọkan Abubakar T. Balewa.

Ninu iwe miran ti Oloye Awolọwọ kọ si Ọlọla A haji Abubakar, Oloye Awolọwọ si sọ pe, Ti o ba ka m i ma awọn eniti kan to fẹ da rogbodiyan silẹ lori ilẹ ede yi, emi ko si pẹlu rara ati ue mo si ri ọkan mi gidigidi pe emi ko si n i ero iru bẹ likan a t i pe gbo bo e r o ọkan mi si yatọ si iru eleyi pata pata.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLOWO

ẸSUN NIPA DOKITA MAJA

Oloye Awolọwọ tun fi ye ile ẹjọ pe ni akoko kan ninu ọdun 1960 pe Patrick Dokotri si wa ba on ni Iba dan o si fi e ta nip Dokita maja sun on.

Oloye Awolọwọ tun f i ye ile ẹjọ fun ipe ti Dokita Maja p e ọgbẹni Patrick Dokotri l a t i wa b a on (Dokita Maja) ni ilu Eko ati pe Dokita Maja si sọ ni igba na pe on ngbero lati doju Ijọb Apapọ dele pẹlu agbara.

Oloye Awolọwọ tun sọ pe ero na gẹgẹ bi Dokita Maja ti sọ yio jẹ igba ti ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba yio ṣ e ipade larin oṣu kẹjọ ọdun 1961.

Oloye Awolọwọ tun sọ pe ọgbẹni Dokotri sọ fun on pe ki ero na to le yọri oni Dokita Maja sọ pe on nfẹ eni ti yio da rogbodiyan silẹ ni Ipinlẹ Ariwa ati pe lati le ti ibọ ko ohun ọṣ wọ ilu ati le ṣe awọn iṣẹ ra ni ilu Eko.

Oloye Awolọwọ sọ pe on fi ye ọgbẹni Dokotri pe on ko ni nkan'an ṣe pẹlu Dokita Oladipọ Maja ati pe on ti ṣe ikilọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ lati sọrọ ni ọdọ Dokita Maja nitori enia to jẹ onjamba lo je

Oloye Awolọwọ tu sọ pe Dokotri tun sọ fun on pe Alhaji Ibrahim Imam ati Joseph Tarka si lọ si ọdọ Dokita Maja ni Eko lati l... o...o

Oloye Awolọwọ tun fi ye ile ẹjọ pe on pe awọn meji-ji ni ikọkan lati ṣe iwadi ọrọ na sugbọn oni Ọgbẹni Joseph Tarka sọ otitọ fun on pe on gba owo lọwọ Dokita Maja ati pe o sọ fun on lati le fi da ẹgbẹ awọn ọdọ silẹ ni agbegbe



Alhaji Ibrahim Imam

ipinlẹ Ariwa Oloye Awolọwọ sọ pe Alhaji Ibrahim Imam kọ dele lati sọ otitọ o ni Imam sọ pe on ko gba owo kankan lọwọ Dokita Maja

Oloye Awolọwọ pe on lọ si ọrọ ea sun baba Maja ni pa ero ti ọgbẹni Dokita Maja sọ pe Dokita Maja gbenro lati ṣe

Oloye Awolọwọ sọ on sọ fun Dokita Akiola Maja ni pa nkan ti ọmọ rẹ Dokita Oladipọ Maja ngbero lati ṣe loju oloye Gbadamọsi ati oloye Akintola

Oloye Awolọwọ sọ pe Baba Dokita Oladipọ Maja Dokita Akiola Maja sọ fun on pe on pẹlu ọmọ on ki nki ara wọn

oloye Awolọwọ sọ pe nwọn mu Dokita Oladipọ Maja wa ba on ni Ikẹnẹ pe Oloye Gbadamọsi lo si mu Dokita Oladipọ Maja wa si ọdọ on ni Ibadan

Oloye Awolọwọ sọpe on kilọ fun Dokita Oladipọ Maja nipa ero to ngba ati ati pe ki o ma se lọkan la ti se iru nkan b, r ra ati pe on to lewu pupọ ni nkan to ngbero na

oloye Awolọwọ sọ pe Dokita Oladipọ Maja ṣeṣẹ sọ fun on pe on(Maja) ko ni e iru nka nbẹ mọ ati pe on ti yi ọkan on pada.

Nigbati oloye Awolọwọ nba ọrọ awijare rẹ lọ o ni ninu ipade awọn agba ti wọn se n uu ile Isimi ni Ikẹja ṣe on bu ẹ u ẹtẹ lu loye Akinta lori akiyan rẹ nipa ọrọ selu

Oloye Awolọwọ sọ pe ni nu ipade on tun bu ẹnu ẹtẹ lu oloye Akintola nipa iro ti npa mọ on ati pe lati le gba olori ẹgbẹ Afẹnifẹre lọwọ on



Ọlọla Ade. Ademọla

oloye Awolọwọ tun daru kọ oloye Ọshuntokun Ọrẹdẹhin ati oloye Duro Ogundiran ninu awọn ẹri to jẹ ọrọ na se oju won

Oloye Awolọwọ sọ pe ki Oloye Ọshuntokun to sọ pe ipade ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Jos bi Ọgbẹnj S B ti sọ fun on pe oloye Akintọla ni on yio si wa nipa gẹgẹbi nwọn y o se da ẹgbẹ na si ọna meji larin Akintọla ati on oloye Awolọwọ

Oloye Awolọwọ sọ pe Ọgbẹni Okoro ti sọ fun on pe oloye Ọshuntokun ti so pe Oloye Akintola ni yio bori mitori pe Alakoso Ijọba apapọ Naijiri si wa lẹ rẹ

Oloye Awolọwọ sọ pe ninu ipade awa alagba ẹgbẹ Afẹnifẹre pe oloye

Wo Oju Ewe Kẹfa

# IWE SI OLOTU

## Eyin Omo Ijesha E Ronu

Olotu, inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye ranpe ninu iwe yin oloyinmomo lati ba awon omo ile Ijesha soro lori aye ati ipo ti awa omo Ijesha wa loni

O je ohun itiju pupo lati ri pe lati igbati Oba ile Ijesha ti waja ni nkan bi odun meji sehin, awon Afobaje ile Ijesha kuna lati je Oba miran dipo eyiti o ti waja

Ti a ba gbe Oye wo a o ri pe o ti to Oba meji to ti waja lehin Oba Ileshe ti awon ara ilu na si ti je omiran dipo ti won, O je ohun ti ko dara rara, Ese ti awon omo ile Ijesha ko fi ni emi isokan ati ifowosowopo lariu ara won ki nwon ti yan Oba miran lati ojoyi ?

Eyin omo ile ijesha nibi gbo gbo ni orile ede yi, o di owo yin o ki e mojuto ilosiwaju Ile Ijesha o, e mase jeki a di ero ehin larin awon ilu yoku ni Ipinle yi o

nu mi yio dun bi eyin omo ilu Ijesha ba le ronu leti tete yan Oba titun ati lati fi eni to to to si ye ki o je Oba na bayi.

Olotu, mo dupe pupo fun aye ti e gba mi.

Emi ni,
S. O. Famiyesin,
Rico Boy,
ILESHA.

## Eleyi Nfe Amojuto Olopa

Olotu jowo ma sa lai gba mi ni aye die lati kesi Olopa ti ilu Ijebu Ode lati ba wa se itoju awon nkan nwonyi ekini ni awon Olosa ati ekeji ni awon Onimoto to ma nlo si ona Epe ati Mushin Awon Onimoto to aa nlo si awon ona nwonyi ko si bikita fun awon enia to ma mo moto won nse ni awon Direba ja ndaku yi si ma nwa mo won gegebi o se wu won ati pe are ti nwon ma nsa loju ona na ko si dara rara. Inu awa ero to ma nlo si awon ona nwonyi yio dun bi awon Olopa ba le ran wa lowo lati le gba wa lowo awon Direba nwonyi.

Ekeji nipa awon Olosa to wa ni ilu Ijebu-Ode ti nwon ko si je ki awon Onile raye gbadun to ba ti di oru ti awon Olosa na si ma lo fole Onile ti nwon ba ti mo pe nwon ti sun tabi ko si Onile ni ile Ejowo enyin Olopa e gba wa lowo awon Olosa nwonyi.

Mo dupe pupo Olotu afinde ara yio na je.

Emi ni
J, A, Abiodun
EKO

## Enyin Omo Oduduwa O Di Owo Nyin O

Olotu inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye die ninu iwe nyin lati ba awon omo Oduduwa soro lori aye ti a wa laseko yi.

E je ki a ronu ki a le mo ibi ti a nlo nitori loju temi o dabi eni pe a ko mo ibi ti a nlo bayi.

Idi re ti mo fi so eyi ni pe opolopo lo mo oro pe nkan atata ni nwon ma nse nigbati nwon ba nkegbe AWO! AWO!! AWO!!! Mo fe fi ye nyin pe ti a ba nkegbe AWO lojojumo ti a ko ba mo ibi ti a nlo o dabi eni pe a ntan ara je ni patapata.

Gegebi a se le mo ibi ti a nlo ni pe ki a dibo fun egbe Olope ki Oloye Awolowo le jade ninu ogba ewon to wa ki a ma se gba egbe kankan laye ki o ma ba je pe nse ni a fe ta ile Yoruba fun awon ile miran.

Ohun ti mo fe ki e fi sokan ni yen ki ise pe ki a ma kegbe lasan lo le mu Baba wa Awolowo jade nitori idi eyi e je ki a tete mo ohun ti a o se.

Emi ni,
S. O, Famiyesin
MUSHIN.


# EGBE IMOLE AIYE

Ipade gbogbogbo yio wa fun gbogbo enyin omo egbe Imole Aiye ni ojo Aiku ti ise ojo ketadinlogbon osu yi (26/7/64) ni nomba 16, Bamgbose street, Lagos ni deede agogo meji osan.

A be enyin omo egbe lati mu ipade na ni oranyan lati wa, nitori ipade na se pataki julo paapa o tun je ipade ti a jiroro lori awon nkan pataki fun ilosiwaju egbe Bakanna, ni a o si pin iwe egbe ati iwe ofin fun awon omo egbe gbogbo. Jowo mase alai ko wa o ki o si tun so fun enikeji ti ise omo egbe Imole Aiye bakanna.

A o si tun nfe omo egbe si lokunrin abi lobinrin.

Ki e tete de

LATIFU BABALOLA
Akowe Agba

# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Granantee Neat Work And Quick Service

**Modupe Printing Press**

**16, Bamgbose Street**
Phone 21985, Lagos.

# I. C. M. Toniki (100 Tablets)




Gbiyanju lati ma lo I. C. M. TONIKI nigbagbogbo I. C. M TONIKI o wa fun Okunrin, Obinrin ati Alaboyun pelu. I. C. M. Toniki e dara fun aini eje to lara, o nfun ni lagbara, o si ntun eje se daradara. Bere fun eyo igo kan, tabi dosini. odidi Apoti (50 dozes) wa pelu. Ilera ni ogun oro o Bere lowo Elegbogi Oyinbo ti o wa ni adugbo re fun I. C. M. TONIKI (100 Tablets.)

Tabi ki o wa si odo:—
MOSOBALAJE MEDICINE STORES,
37, Palmchurch Street, LAGOS.

GBOGBO ARA ILU NKO ORIN IYIN ati AYO NIPA "DYNAMIREN" TONIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Toniki Jamonu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mo daju fun Ako aggbara ati Ajebidan ise Re lara Agbalagba Okunrin gbogbo"

Bi are ara ba nmu o, nigbakugba fun wahala lala sisese ti o ko ie jeun daradara, tabi ki o male sun dada okun losan tabi loru tabi awon isan ara re gbogbo ki se fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunle daradara won ise tabi wahala sise tabi fun awon ailera gbogbo 'nyin ti ojo ori re (age) ba ti koja Ogbon odun o si de adorin tabi jube lo. Mo dupe "DYNAMIREN' ni egbogi ti e nfe lati so ara di otun patapata oju re a si jolo, eran ara re ti o ti hunjo yio bi e s'i dan pada. Ara re yio ma gbe kankan nigbakugba y'Are" nigbakugba yio salo pelu igoaaba-dun ati alafi diro de o. Iyen daju Bere Egbogi na ni Sobu: awon

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4. Tinubu Square Lagos
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos.
Phone: 22878 Naijiria, (Oja Ita Faji)

# Ijọba Ibilẹ Da Owo Ọba Olukarẹ Daro

IKARE:— Ni ọjọ'Ru ti ṣe ọjọ Lejidinlogun oṣu yi ni irohin de etiebọ wa lati ilu I' ar ti a tun gbọ pe Ijọba Afunishọ ti Ijọba Ibilẹ ilu Ikarẹ tun gbero lati da owo oṣu Ọb Momọh keji Olukarẹ ti ilu Ika ẹ duro fun odi-ndi ṣu mẹfa.

Awọn Igbimọ Ijọba / funishọ ti Ijọba ibile ilu Ikarẹ na tun gbero lati din agbara Ọb na ku gẹgẹbi alaṣẹ lori awọn Oloye to wa lab rẹ ati pe ko gbọ-dọ paṣẹ kankan lori awọn Oloye na.

Gbogt o agbara to yẹ ki Ọba na ma a lo lori awọn Oloye ilu Ikarẹ yio si jẹ pe lati ọwọ awọn Igbimọ Ijọba Afunishọ ti Ijọba Ibilẹ ilu Ikarẹ ni yio ti ma wa.

Ninu ẹsun ti awọn igbimọ Ijọba Afunishọ na fi kan Ọba Momoh keji ni pe o ni ọwọ ninu ọrọ oṣelu ati pe igba gbogbo lo jẹ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan si fi Aafin Ọba Mo-mch keji. Olukare ti ilu Ikarẹ nṣe ibi ipade lati gbero nipa ọrọ eto oṣelu.

Awọn igbimọ Afunishọ na tun fi esu kan Ọba Momoh pe o lo agbara rẹ lọna ti ko tọ lati ma yọ awọn Oloye kan kuro lori oye ati pe ko si ni ri ẹsun kan to fẹsẹ mulẹ eyiti to jẹ wipe idi nkan to fi yọ awọn Oloye na kuro lori oye.

Nigbati oniwe irohin wa lọ si Aafin Ọba na lati lọ se iwadi lẹnu rẹ oniwe irohin wa ri ye ni pe on ko ri Ọba na lati le ṣe iwadi ọrọ na lẹnu rẹ.

# Ye Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan. 22 - Feb. 20) Ire yio jẹ tirẹ lọjọ oni, laju si'lẹ, ki o si ma sọ alafia ara rẹ, botilẹ jẹ pe ara rẹ ko le tobẹ.

PICES (Feb. 21 - March 20) Ohun ti o dara ni pe ki o tun rere ajọsọ iwọ pẹlu ẹnikan ti o ti ni, lọjọ piṭẹ sẹhin. iwọn yi ni irohin ti yio ṣe o ni anfani gbọ

ARIES (March 21 - April 20) Ero ọkan rẹ yio lodi si awọn to yi ọ ka ma ṣe fi ori kikun sọ pe lori are lo wa, ki o ma ba ni ṣoro pupọ

TAURUS (April 21 - May 20 Ọkan ninu awọn ero ọkan rẹ yio sipaya, ṣugbọn ṣọra nipa ero ti o ngba lọkan ire ati ayọ mbẹ fun iwọ bi o ba mba awọn ti o ni fẹ lo po.

GEMINI (May 21 - June 21) Laju si lẹ ki ọ ma sọ ohun ti ba dara jẹki ọkan rẹ fa si wọn, Idunnu ati ayọ yio si wa fun ọ ni ọjọ ale.

CANCER (June 22 - July 23) Wahala kan yio de si ẹnin ara rẹ tiju ara rẹ gidi gidi ki o ma ba ba ayọ ọjọ na jẹ tabẹ t inu yio ma bi gbogbo awọn en a ti o yi ọ kan si ọ.

LEO (July - Aug 22) Ṣọra nipa irokuro rẹ, bi o ba lọ daba buruku kan, ewu mbẹ fun ọ ki o ma ba fi ọgbọn ti o ni ba nkanjẹ.

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Ire mbẹ fun ọ rẹpẹtẹ loni, jẹki ẹri ọkan rẹ ti o lọ sibi o fẹ. Aisan kekere leṣe ọ loni, sa ṣe jẹjẹ.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Aiye rẹ yio dun bi oyin, ọjọ oni yio si dun fun ọ. Ohun kan ti iwọ ko nireti yio mu ọ lati pa ere rẹ da, ire ni akẹhinsi rẹ yio jasi.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Maṣe gba imọran kan si ara rẹ ti o lewu ki o si ṣọra rẹ nigbati o ba fẹ rin iri ajo, nitoripe ewu nbẹ loju ọna, yio ṣoro fun ọ lati ta ẹnia ṣe ṭọ.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ṣọra, aṣiṣe kekere ti o ba ṣe o le di nla ṣugbọn alẹ oni yio le koko ma a ṣe akiyesi ohun ti o ngbọ ati ohun ti o nsọ, ati iru iwa ti o ma hu, o dara ki o le ṣe aṣeyanju ninu ọkan ninu awọn ohun ti o gbalero.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Iwọ yio ma ṣe Layefi lori irohin kan ti o gbọ loni igbarere yio si de si ọ, Iwọ yio ri ere ọja rẹ,



# UROLYSAN DRAGES'

Fun Itọ u tabi fifọ Apo Ile Itọ (Kidney-Bladder) fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu, ẹhin didun Ibadi Gige tabi riro, eri ile itọ, tabi itọ-jijo eniaito rirun, rukuruku Pipọn, aikoleri itọ lati tọ to, lakuregbe, orunkun ọwọ, ẹsẹ, Ejika wiwu tabi riro



Ara sisan. titobiju aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia didaji loru nigbakugba, ati orişirisi awọn aisan tabi amodi, ba wọn. yi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Mejirẹlo si ni ilu Naijiria nitorina ṣọra ki awọn eleru tabi awọn ori rọbirọbi ma ta orişi omiran ti ko ni lari fun ọ. maṣe gba rara! Owo rẹ jẹ Sile mẹfa abọ 6/6d owo Ọkọ Silə kan abọ (1/6d)

Bere Egbogi yi ni ṣọbu awọn:-

NIGERIA MEDICINE STORES
4. TINUBU STREET, LAGOS. PHNE 20278
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos.
hone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# Awọn Ọja Ajẹbidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin titẹ Etutu ẹṣẹ ẹbọ pupọ ati egbo ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku ọmọ ọkọ lẹnu mọ oso ati ajẹ ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ni ohunkohun toba si dawọ rẹle ni yio ja si rere awọn baba awọn ti o gbowo gba asọ lọwọ enia ko ni ri gba mi Iye owo rẹ 20/-

Iwe egbogi ajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko ṣe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe yi lọwọ ṣ ṣa arun ni o ko ni le wo ko si ni ijaya pe arun tabi mimu. ọ a si ka le pa ọ Ive owo 25/- a larin Ẹyọ Ajẹ ti o ba nfin turari yi ba a ti ṣe ure rẹ Ajẹ ati abatẹnijẹ ko ni foju si ọ lara ohun ṣohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwe ko mọ aita ọja agbaua ko si ni wọ igba rẹ idabobo ki o siwa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| Pa golo kan | 10/6d |
| Kekere | 2/6d |
| we Gbedegbẹyọ Hausa | 3/ |
| Itumọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Eewo ilẹ Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 3/6 |
| ati agbara Psalm ẹgun lori awọn Ajẹ pẹlu Ara | 30/- |

# APEJUWE ILE IṢẸ WA

Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ti ile itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja niadirẹsi mi niyi:—

Akiyesi Pataki:- ale ri awọn iwe wọn yi ra ni garage Iddo, Mushin, Ikorodu road ati gbogbo ile itaja iwe Ti o ko ba ri i ra wa si ọdọ mi ngo ta fun.

**J. O. Shoyinka**

c/o Postal Agent,
1, Isiba Street
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

# Ọtẹlẹmuyẹ Nki Nyin

ỌTẸLẸMUYẸ nki nyin o, ẹ ko ni kagba ko o, agbako ko ni ko nyin o, ẹ ni ẹlẹni ko ni gbo iṣẹ nyin ṣe lagbara Baba loke Aṣẹ. Mo ti ṣe ileri mo si ti pinnu lati tuna asiri awọn Babalawo, Oniṣegun ati Adahunṣe opurọ

## AWỌN OPURỌ BABALAWO

Hal o se, o ma tilẹ ṣe o, aiye ti bajẹ doju rẹ gan gbogbo awọn ọmọde ti o wa iṣẹ ti, ni awọn sọ ara wọn di Babalawo ọsangan naẹn ko mọ awọn ugbalagba awọn papa ntan enia jẹ. Hal lọwọ onijibiti Babalawo, Odua gba wa o.

Gẹgẹbi ẹnyin papa ti mọ pe ni ile aiye ti a wa yi, ko si ẹniti idaamu g de ba o nba Oba ori itẹ anbọsibọsi Talaka. Nigbati idaamu ati jẹ, airinu de ba emi Ọtẹlẹmuyẹ, mo gbera sọ, o di ile Babalawo kan lati lọ wadi ohun ti o fa idi iwọnyi—nko tilẹ ti sọrọ ki o to so pe ki ndamyan pẹlu sisi (6d) sinu awo. Mo woke, mo wolẹ ko si ju sisi (6d) lọ lọwọ mi, mo so sinu ara mi pe, ko si ẹniti o ran mi wa, emi ni mo ran ara mi wa ni diju mọri, mo ju sisi sinu awo pẹ.

Ẹniti ti ju owo sinu apo rẹ kowo, o bẹrẹsi purọ, o ni ri oto, mo ni kini yẹn? o ni nkan ti on ri loju opọn na ni pe ki nṣọra gidigidi. nitoripe ọkan ninu awọn iyawo mi mẹtẹta fẹ fun mi ni Ogun jẹ, o ni a bi bẹ kọ? mo ni irọ ni baba, o kan wo sun, o ni iyawo mi ti o loyun yio bi ọmọ kunrin, ọmọ na yio jẹ olokiki lẹjọ aiye rẹ, ṣugbọn ki nma jẹki ẹnikan gbe, a fi Iya mi nikan ṣoṣo, iyawo mi bimọ Obinrin ni o bi silẹ janto, ati ẹjọ ti o ti purọ fun mi ni inu ti nbi mi pe, ti o ba ja si irọ, ngo da sẹria fun baba yi.

Mo gbọnra nu gau, o di ile Babalawo, paṣan atori to jire wa labẹ agbada mi, mo ni baba sisi mi ijọun da? o ni sisi kọ, sisi ni, ki o to yira pada ọwọ ẹgba ti tẹ ẹ, a o na enia to eleyi ri, mo na kisa si l ra, ṣugbọn o jẹ sisi mi gun.

Ẹ ṣọra lọdọ awọn onijibiti Babalawo o.

## IFA LO NI NJANDIMỌ Ẹ O DI BAMU

Bi mo ti sorikọ ti mo nbo ni mo pade ẸKU AIIJỌ mi, o da mi duro o ni kinde ti oju mi fi koro bayi? mo ko mo ro fun un o rẹrin kakaka o ni kekere ni ti emi, Iya to jẹ on loni ko ṣe fẹnu sọ—Mo mi, mo mi kanlẹ hẹn, mo ni ti lo ri? o ni, on ti wa lọdọ ọko ou e ti le ni ọdun meje, ti on ko bimọ, o ni nigbati on ro ọrọ yi titi at jẹun diṣẹ, ni on ba fi ọrọ yi lọ ọrẹ on kan.

Gẹgẹbi ọrẹ imule o juwe ile Babalawo kan fun on pe ki baati, ti o ba ṣogun fun on, on yio bimọ, gẹgẹbi ẹ ti mọ iwa emi Ọtẹlẹmuyẹ pe, nki ṣai wadi ọrọ de okodoro, mo tun bere lowọ re pe ki lo tun ṣẹle? O ni nkan keji ti on ri sipe Babalawo bẹrẹ si difa, o gbe ọpẹlẹ lulẹ pẹ ẹ, o ni ohun ti o yọ loju ọpọn, ṣe on le ṣe? o ni on sọ pe on yio ṣe e, o ni Babalawo naa bayi pe Ọbaranbakumọ Ifa lo ni njadi mọ o, o di pau, o ni ki on to yi pada. Babalawo ti san on lara, ẹsẹ on mejeji loke, ni kukuru, Babalawo ti ṣe mẹgẹmẹ, mo rerin mo takiti, ni idakeji ẹwẹ, mo si tun ka ti awọn Obinrin alaimọkan ti awọn nwo iṣẹ lọwọ awọn Babalawo ati rọta wọnyi.

Eyi ni lati mu wa si eti gbọ awọn ẸGBẸ AWO PATAKI ti ilẹ Naijiria ki n on tete mojuto ọrọ yi ki awọn okugbẹ wọnyi ma ba iṣẹ wọn jọ—ko si ọmọ karọ-o-jire ti yio pe Babalawo, ko si tabi ogun ko si. Ẹnyin Obinrin ti ẹ si fi ile Babalawo lilọ ṣe apata, ẹ ṣọra lọdọ awọn Babalawo "IFA LONI NJANDI MỌ Ọ" Emi Ọtẹlẹmuyẹ ko sọ pe Babalawo ko si o, ẹnu mi ko gba lati sọ bẹ o, ṣugbọn awọn Babalawo Eke ni mo nba wi o.

Ọtẹlẹmuyẹ n'agbefọ—ẹran lọ o. Lọsẹ to nbọ lagbara Odua ngo kan awọn ASAPẸ MUSHIN ati MOSEWELE lara ngo si jẹki Ọlọpa tọju bọ ọrọ wọn.

Awọn Alafarawe Babalawo ni mo mọnipa rẹ, ki iṣe awọn Babalawo atata o.


REMAIN YOUNG
100 YEARS
Details:-Add.
C. T. Hospital 1, (R.Y)
Azad Market, Delhi
6, India



BI O BA NI
**Iwe—Titẹ**
FUN
**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişiriṣi iwe Itufọ tabi ijade Oku**
ATI
**Iwe Igbeyawo**
KOWE SI ILE—IṢẸ—ERỌ ITẸ IWE
**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO POỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
Oun wa wo Iṣẹkan ṣo ko si ri iyato



NGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!!




Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lenu on akan bi ọdun kan tabi jubẹ lo awọn egbogi rọ! irọbi fun le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara. lu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun Iko otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaya, Iko iile. Ikọ ti o mọ mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungsa tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba ran Igo kan PORAL yi wa Iwo a yio ri iyato ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jeun daradara iwọ yio si un fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisiri i Ẹ̀bọ gi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square, Lagos
WATERLOO MEDICINE STORES
9, Palmchurch Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ojalta Faji)

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba
ATI NI AWỌN ṢOBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY
IBADAN

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No. 751, THURSDAY JULY 23. 1964 (2D)


## Ọmọ Kunrin kan ku Sinu Yara

EKO

Jinijini dabo As ju ilẹ Dammark ni Naijiria ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi nigbati awọn oṣiṣẹ to wa labẹ rẹ fa igbe ta ti nwọn sọ fun pe ẹdẹmọkunri kan Newton Abel ẹni ọdun mẹdọgbọn pe o ku sinu yara.

Gẹgẹbi irohin ti awọn alaba sişẹ pọ ọmọ kunrin na ti fi ye oniwe irohin wa to lọ si adugbo ile ibi ti Aṣoju fun ile Denmark ni Naijiria ni nọmba 2a, Rumsey road, Ikoyi fi ye ni pe ọmọ kunrin na si wa ninu yara to ngbe ni ilẹ Ajoji na, ṣugbọn nigbati awọn iyoku rẹ ko ri ni nwọn ba lọ si ilẹkun yara rẹ ti nwọn ti ba Newton Abe o fi ku sinu yara.

Newton Abel si jẹ olutọju ile Aṣoju fun ilẹ Denmark in Naijiria, Oniwe Irohin wa fi ye wa pe Aṣoju ilẹ Denmark ni Naijiria sọ fun on pe iyalẹnu ni iku Newton jẹ fu . on patapa.

Irohin tun fi ye wa lati teşan awọn Ọlọpa ni Ikeyi pe ni bati awọn ṣe ayẹwo ara rẹ awọn ko ri apa pe boya enia kan ba ja tara, Awọn Ọlọpa si ti gbe oku rẹ lọ si ile iwosan lakuiaku

# IJA NLA LORI ẸNI TI YIO RỌPO ỌBA ADELE

EKO:— Ni Irọlẹ ana ni irohin de ọwọ wa lati Igaidunganran pe ọpọlọpọ awọn idile to lẹtọ lati jẹ Ọba ilu Eko lo ti njadu pe awọn ni yio rọpo Oloye Ọba Adeniji Adele keji to w'aja laipẹ yi.

Ọpọlọpọ idile to ni ẹtọ lati jẹ oye Ọba ilu Eko lo ti nmura lati yan enia kan ninu idile wọn lati le fihan gẹgẹbi ẹniti yio jẹ Ọba nigbakugba ti nwọn ba ti gbe wọn lati mu ẹniti yio jẹ oye Ọba ilu Eko.

Ninu awọn idile to lẹtọ lati jẹ oye Ọba ilu Eko ni awọn idile Akinsemoyin, Esinlokun, Adele, Gabaro, Dosunmu ati Tadeyọ Olusi.

Ninu ọrọ ti oniwe irohin wa ba alagba idile Esinlokun, Oloye Aminu Kosọkọ, Asajon Ọlọja ti lu Eko sọ nipa ẹniti o yẹ ki o rọpo Ologbe Ọba to w'aja ? Oloye Aminu fi ye oniwe irohin wa pe on ko ni itare si ọrọ nipa ẹni to yẹ ki o gun ori oye Ọba ilu Eko.

Oloye Kosọkọ sọ pe on ko ni kọ sẹnu awọn enia ti nwọn ba kesi on lati wa jẹ Ọba ilu Eko.

Olori idile Akinsemọyin oloye Durorike Akinsemyin tun fi ye oniwe irohin wa pe ibile on lo ye ki o rọpo ọba Adele oloye Durorike Akinsemọyin Erelu ti ilu Eko tun sọ ninu ọrọ rẹ fun oniwe irohin pe awọn idile on lo ye ki nwọn mu ẹni ti yio jẹ ọba ilu Eko sile bayi

Nigbti Erelu ilu Eko nba awọn oniwe irohin sọrọ ni Isale Gangan ni irọlẹ ana lo si nso itan ọba ilu Eko lati ọba Ado ti 1630 ti de as ko ologbe ọba Adele to w'aja laipẹ yi.

Oniwe irohin tun fi ye wa pe awọn afọbajẹ ilu Eko si ti pinin lati sẹ ipade lori eni to yẹ ki o rọpo Ọba Adele to waja laipẹ ni ẹsẹ kini oṣu ti nbọ ni nwọn yio sẹ ipade na ati pe awọn afọbajẹ ilu Eko si ti sọpe gbogbo eto nipa isinku ọba Adele to waja yio pari ki awọn to le ṣe ipade.

Irohin tun fi ye wa pe awọn afọbajẹ na ti sọ pe awọn yio yan ẹniti yio rọpọ Ologbe Ọba Adele lẹsẹkẹsẹ ti nwọn ba ti pari eto isinkun ọba Adele to waja.



Ologbe Ọba Adeniji Adele Keji

Ija lorin awọn afọbajẹ ilu Eko si ti pari lẹhin ti apapọ Ijọba ile Naijiria ti da awọn Oloye oni fila funfun duro lori oye ninu oṣu kẹjọ ọdun 1962 nigbati Ologbe Ọba Adeniji Adele ti fi ọwọ s pe ki Ijọba apapọ yọ awọn Oloye na kuro lori aye. Ologbe Ọba Adele si fi ọwọ si pe ki nwọn yọ awọn Oloye na lẹhin igbati ede aiyede bẹ silẹ larin Ologbe Ọba Adele ati awọn Oloye na.

## Ekunrẹrẹ Idajọ Oloye Awolọwọ (Apa 9)

LATI OJU EWE KEJI

Orẹdẹhin sọ pe Oloye Akintọla s l ju oloye Ọshuntokun ati oloye Ogundiran pe oloye Akintọla ti sọ pe oloye Awolọwọ ti ngbero lati da oju Ijọba apapọ delẹ.

Oloye Awolọwọ sọ pe olo oloye Ọshuntokun ati oloye Ogundiran si parọ Pe oloye Akintọla ko sọ ọrọ to jọ bẹ mọ on oloye Awolọwọ

Oloye Awolọwọ sọ pe on ko ba ẹni kan kan Imam tabi Dọkotri sọrọ nibi kan tabi nibikibi gbero lati gbogun tabi ki on sọ pe on yio doju Ijọba delẹ.

Oloye Awolọwọ tun fi ye ile ẹjọ pe lẹkan ṣoṣo ni on ba Ọgbẹni Oleari pade ninu ọjọ aiye on ati igba kan ṣoṣo na ni oṣu kẹjọ ọdun 1962 ni adugbo numba 7 Bell avenue.

Nigbati Ọgbẹni B A. Adedipẹ bere ọrọ lọwọ Oloye Awolọwọ, o sọ pe igbimọ Amoye ti ẹgbẹ on da silẹ pe awọn enia to wa ninu igbimọ na ni Oloye Samuel Akintọla, Ayọtunde Rosiji. Oloye Anthony Enahoro ati on (Awolọwọ) gẹgẹbi ala ga igbimọ na.

Oloye Awolọwọ tun sọ pe ki iṣe otitọ nipa ọrọ ti nwọn so mọ on (Awolọwọ) Samuel Ikoku ati Oloye Enahoro pe awọn ngbero lati gbogun ti Ijọba ati lati le doju Ijọba ilẹ Naijiria bolẹ ati pe gbogbo wọn lo sit ni igbẹkẹle ninu Ijọba fun gbogbo enia.

Oloye Awolọwọ tun so pe Dọkita Ọnabamiro ti jẹ ẹlẹri Ijọba pe oti wa tẹlẹ pẹlu ẹgbọ N C N C ati pe ko ti pẹ to ṣẹṣẹ di ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ.

Oloye Awolọwọ sọ pe Dọkita Ọnabamiro ko pẹlu igbimọ Amoye ẹgbẹ Afẹnifẹre ati pe Dọkita Ọnabamiro wa si ile ẹjọ lati wa jẹri eke mọ mi (Awolọwọ) Ọrẹdẹhin sọ pe oloye Akintọla sọ loju Oshuntokun. ati oloye Ogundiran pe oloye Akintọla ti sọ pe oloye Awolowọ ti ngbero lati da ogun silẹ ati lati doju Ijọba apapọ delẹ

Oloye Awolọwọ sọ pe oloye Oshuntokun ati oloye Ogundiran si purọ pe oloye Akintọla ko sọ ọrọ to jọ bẹ

Oloye Awolọwọ so pe on ko ba ẹni ka kan Imam tabi Dokotri sọrọ nibi kan kan tabi nibikibi gbero lati gbogun tabi ki on sọ pe on yio doju Ijọba delẹ


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 23/7/64.